IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 590 MONDAY APRIL, 27 1964 (2D)

## Ọkunrin Kan Ji Agutan Gbe

AGEGE:— Oju gba gbogbo enia ti fun awọn meji kan ti awọn Ọlọpa Ikẹja mu ni irọlẹ ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ kọkanlelogun oşu yi, nitoripe awọn ọkunrin na ji aguntan Alhaji Busri gbe nibiti o gbe nta awọn aguntan na ni ọjọ Agege ni irọlẹ ọjọ na.

Ọga awọn Ọlọpa Ikẹja fi ye oniwe Irohin wa Ejon'gboro ni irọlẹ ana wipe, awọn ọkunrin mejeji na wọ ọkọ Reluwe lati Ifọ, nigbati nwọn si de Agege ni nwọn ba sọkalẹ.

Bi awọn ọkunrin na ti sọkalẹ işọ awọn ti nta ẹran larin ọja ni awọn mejeji lọ, ni nwọn ba bẹrẹsi yọwo ẹran, bi nwọn ba yọwo ọkan ti nwọn ko ba gba, nwọn a kuro lọdọ wọn lọ ibomiran

Şugbọn nigbati nwọn de ọdọ Alhaji *Bu*sari, ti nwọn yọwo ẹran kan lọwọ rẹ- Alhaji na ni *ki* nwọn duro de on ki on sare lọ sọ fun ẹniti o jẹ Ọga on, *n*itori pe iye ti ẹran na ba de Agege ni nwọn fẹ san fun un.

Nigbati Alh*aj*i na lọ sọ fun ẹnikeji rẹ, nigbati yio fi de, awọn ọdaran na ti tu agutan meji ai ori işo, nwọn si ti sare lọ wọ moto ti nlọ si Ọtta ki Alhaji na tode

Nigbati o de ti ko ri awọn enia na, ko si tun ri meji ninu awọn ẹran aguntan ti o nta ni o ba sure wa awọn enia na lọ, nibiti moto na duro si ni oke ile epo moto ni o ti ri wọn mu, nwọn si mu enia na lọ si Tesan Ọlọpa Ikẹja.

# ẸJỌ AWO TUN BẸRẸ L'ẸHIN ISIMI ỌDUN ILẸYA

EKO :- Ni ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ kọkanlelogun oşu yi, ni ile ẹjọ giga julọ fun Orilẹ-ede yi, şiwọ ninu işẹ wọn fun isimi ọdun Ileya, ti nwọn si gba isimi ọdun na lẹhin igbati diẹ ninu awọn agbẹjọro ti o ngbẹnuşe fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti ba Ijoko awọn adajọ sọrọ lori ohun ti nwọn pe ni iwa aidara ti adajọ ti o şe ẹjọ na kọ lori idajọ ti o şe, gẹgẹbi o ti şe şi Ofin lo ti o si şe idajọ yatọ gedegbe si ohun ti awọn Olujẹjọ na ro niwaju rẹ.

Ẹniti o kọkọ ba Igbimọ Ijoko awọn adajọ na sọrọ ki nwọn to gba isimi ni Oloye Ọjọgbọn Amofin, Ọgbẹni Victor Durand.

Ninu ọrọ rẹ, o fi han ile ẹjọ pe, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ko jẹbi ẹsun ti adajọ şe idajọ ẹwọn fun un.

O tun şe alaye, lati ran ẹnyin onkawe wa leti' pe Oloye Awolọwọ ko si ni ile, nigbati awọn Ọlọpa lọ si ile rẹ ti nwọn sọ pe, nwọn ri awọn nkan ija ogun ninu ile rẹ.

O ni Eko ni Oloye Awolọwọ wa ni Ikoyi ni asiko ti awọn Ọlọpa lọ si ile rẹ ti nwọn si sọ wipe awọn ri awọn nkan ija ogun ninu ile rẹ.

### AWỌN ỌTA

Bakanna ni Ọgbẹni Durand şe alaye wipe awọn ọta abinugbaiye Oloye Awolọwọ ni adajọ pe lati wa



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

jẹri niwaju Ile ẹjọ ko pe awon ti nwọn mọ nipa Awolọwọ ti nwọn si jẹ ọrẹ tabi ọmọlẹhin rẹ lati wa jẹri niwaju ile ẹjọ.

O tun şe alaye siwaju pe ko si ọna ti enia fi le mọ bi, ki işe awọn ọta abinugbaiye Oloye Awolọwọ ko ni nwọn lọ ko awọn nkan na sinu ile rẹ nigbati ko si Oloye na nile, nitoripe, "Aisi nile Ologbo, ile a ma di ile ekute."

Nigbati Oloye na wa ni nkan bi ibusọ mẹrindinladọta (46 miles) si ilu rẹ, ki ni enia mọ ti o le şẹlẹ ninu ile, "şe bi bale ile ba ku, ile a ma a di ahoro."

Ọgbẹni Durand tun şe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, Dokita Ọladipọ Maja ni o şe eto, gẹgẹbi ẹjọ ti o wa ninu iwe pe on fẹ ko awọn ohun ija wọlu on yio si fọ Ile Igbimọ Aşofin Apapọ Ijọba Naijiria nigbati awọn enia na ba nşe ipade lọwọ.

O tun pe akiyesi ijoko awọn adajọ na si akọsilẹ ẹjọ ti Maja paapa ro niwaju adajọ ati awọn ẹri ti Alhaji Ibrahim Imam jẹ niwaju adajọ Sowẹmimọ ati Patrick Dukotri

### ẸJA PANLA

Ọgbẹni Durand tun fi han ijoko Ile ẹjọ na bi Maja ti şe sọ fun Imam pe on ti lọ si Ghana lati lọ ra awọn ohun ọşẹ, şugbọn nigbati on fẹ ko awọn ohun ọşẹ na sinu ọkọ oju omi ninu ẹja panla, nkan na ko rọgbọ fun on.

O si tun sọ fun Imam pe on fẹ ko awọn ohun



Ọgbẹni Ọdẹsanya

ọşẹ diẹ pẹlu owo gọbọi wa si Ipinlẹ Ariwa fun Ibrahim Imam, şugbọn Imam sọ fun un pe, [illegible] on fẹ

Wo Oju Ewe Kẹfa



Ọlọla Ade. Ademọla

# YẸYẸNATU!

## ONIYẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:- Olotu, hẹwu gbogbo ibiti ẹnyin ba de ni nwọn nlu nyin ni ?

Olotu:- Ẹnyin wo?

Yẹyẹnatu:- Ẹnyin ẹgbẹ Dẹmu nu

Olotu:- Ẹmu wo lẹ nda nu, Ẹgbẹ wo ni mo sọ fun ọ pe mo nṣe

Yẹyẹnatu:- Sebi ẹgbẹ yin, ẹgbẹ ọlọwọ ni njẹ, Ẹgbẹ Dẹmu nu

Olotu:- O-ho, Democratic

Yẹyẹnatu: Ewo lẹ njẹ Dẹmukirati Bi gbogbo nkan ba ndi tiratira fun enia ko saisi orukọ ti ko ni jẹ tan

Olotu:- Kilo ndi tiratira fun wọn ?

Yẹyẹnatu:- Ẹ wo o, Akintọla ni ti awọn ni gbogbo ilu nse ṣugbọn sisa lo nsa kiri bi ole

Olotu:- Ha! o pe Akintọla lole!

Yẹyẹnatu:- Rara nko jẹ pe lole ki i sele mo ni o nsa kiri bi ole ni

Olotu:- Bawo ?

Yẹyẹnatu: Kini se to sa ni Ado-Ekiti ?
Kini se ti ko tun gba Ilesa kọja ?

Olotu:— Ko wun ni kẹ

Yẹyẹnatu:— Igbati o fẹrẹ jẹ gbogbo ibiti o ba de ni nwọn ndaru,

Olotu:— Ṣe o si nse e fun wọn.

Yẹyẹnatu:— O ntirayi o. Ntori ko to gbọ ẹjọ lo ti ndajọ

Olotu:— Tani sọ bẹ fun ọ?

Yẹyẹnatu:— Ṣebi ẹ ri ohun to sẹlẹ ni Ilesa.

Olotu:— Yẹs kẹ, o yan enia meji lati ṣe iwadi kẹ.

Yẹyẹnatu:- Ko to yan wọn nko, ṣebi o ti ile-iwe o si yọ ọga ile-iwe

Olotu:- Yẹs, o lagbara rẹ ni

Yẹyẹnatu:- Ha-ha-h, oga Agbara wo lo ni Ṣebi funra awọn ara Ilẹṣa ni nwọn kọ ile-iwe wọn ṣebi fun Ọdun mẹdọgbọn ni ijọba ko fi ran wọn lọwọ rara, ihalẹ wo ni Baba Dele wa nṣe

Olotu:- Ihalẹ kọ kẹ O dara kini ṣe ti awọn ara ilu turf lọ bẹ ẹ,

Yẹyẹnatu: He! irọ ni ki ṣe ilu lo lọ bẹ ẹ, awọn Ọmọ ẹhin Akintọla to jẹ Ọmọ Ilẹṣa lo lọ nitori ki oju ma ti

Olotu;- Oju titi bawo?

Yẹyẹnatu:- Nigbati nwọn ri pe awọn ara Ilesa fẹ nake kọri pe awọn ko ni da ẹnikẹni lohun ni wọn igbati ọrọ na ko kan awọn Ọmọ ile-iwe ti nwọn da sita ni awọn ẹwẹwa Baba Dele ba lọ fi orukọ ilu bẹ ẹ

Olotu:- Ṣugbọn o ti ile-iwe yẹn ṣa

Yẹyẹnatu: Lootọ ni ntori kini?

Olotu:— Nwọn sẹ iwadi si kẹ

Yẹyẹnatu— Iyọrisi iwadi ni ko si ohun to kan awon Ọmọ ile-iwe ati ọga wọn

Olotu:— Yes mo gbọ bẹ

Yẹyẹnatu: — Ṣugbọn ẹ ma a wo ohun ti yio ṣẹlẹ si awọn to ṣe iwadi yẹn

Olotu:- O yẹs, nwọn ko ni pe ni igbega ni ibi isẹ

Yẹyẹnatu.— Igbega bawo Iyẹn lo wa jinasi wọn nisiyi

Olotu:— Nitori kini ?

Yẹyẹnatu:— Ntori nwọn pe Akintọla ati awọn ẹmẹwa rẹ ni opurọ.

Olotu;— Nwọn ko ma sọ bẹ o.

Yẹyẹnatu:— Lootọ ni nwọn ko sọ bẹ taara ṣugbọn nwọn ni ọga ile iwe ati awọn ọmọ ile iwe lo de na fun Akintọla, awọn oluwadi si ni ọga ile-iwe ati awọn ọmọ rẹ ko mọ ohunkohun ni pa rogbodiyan to bẹ

Olotu:- Olorun yio ko wa yọ, ntori o nse ojojumọ

Yẹyẹnatu:- Ko sewu

Olotu:- Ko sewu? Oni ija igboro ni Ekiti, ana ni Ijebu, ijẹta ni Ilaro, ijẹrin ni Ilesa o ni ko sewu

Yẹyẹnatu:- Ko sewu, ṣe ẹ mọ pe ọjọ ti nwọn ba nju teburu ati ṣiya ni ile igbimọ Ibadan ni a ma nmọ pe ewu nbẹ Bi ina njo ilu, pi nwọn npa enia bi eni pa ẹran bi nwọn ko ba ti ju ṣiya, ki awọn agbalagba ma a bẹ gba windo jade ko si ewu.

Olotu:- Ṣọra rẹ

Yẹyẹnatu;— Looto ni o yẹ ki nṣọra Bi Akintọla ba nṣọ gbogbo ohun ti mo nṣọ yi ko sewu bi o nṣere kiri nisisiyi ti npe e ni "AG RONU" ko ni si ofin lati da a duro ṣugbọn bi enia ba nṣe "AKINTỌLA RONU" tabi "DEM KONU" werewere ni ofin yio de lati gbe mi tanto

Olotu:— Iwọ ko mọ pe eni ba wa nidi pẹpẹ ni nje nidi pẹyẹ ni?

Yẹyẹnatu: Ijẹkujẹ ni yẹn yio si ha wọn lọrun.

# Jesu Kristi Ni Olugbala Gbogbo Araiye

Lati Ọwọ: ASIWAJU PAUL AGBOOLA ỌLADIPỌ

Li ọsẹ ti O kọja, a fi awọn asọtẹlẹ rẹ han wa lati ẹnu awọn Woli, ṣugbọn yio dara lọpọlọpọ bi ẹ ba le fi han wa nipa ọrọ rẹ ati agbara, ati ohun ti iwe Mimọ wi nipa Jesu Kristi.



Ọnapupọ ni Iwe Mimọ ti wi nipa Jesu Kristi ti o si pe e ni Olugbala, lẹhin rẹ ko si tun si Olugbala miran mọ nitori iku rẹ lori agbelebu fun ẹsẹ temi ati iwọ, Bakanna si ni gbogbo ijiya rẹ, Bi awọn ijiya na ti ṣe lọ ẹo ma a gbọ ni ọsẹ to mbọ,

Awọn ẹri ti o fi han wipe Jesu ni Olugbala ni wọnyi Jesu sọ wipe, "Emi ko wa lati ṣe idajọ aiye, bi koṣe lati gba aiye la" Johanu 12 : 47 Jesu ni Emi ni ọna ati otitọ, ko si eniti o le wa sọdọ Baba bi ko ṣe npasẹ mi" Johanu 14 : 12, Ko si igbala lọdọ ẹlomiran nitori ko si Orukọ kan labẹ Orun ti a fi fun ni ninu enia nipa eyi ti a le fi gba wa la Act. 12 : 4. Gba Jesu Kristi gbọ a o si gba ọ la, iwọ ati awọn ara ile rẹ pẹlu Act. 12 : 8 de 31 nitori awa tikalara wa ti gbọ ọrọ re awa si mọ pe nitotọ, eyi ni Kristi na Olugbala araiye Johannu 4: 42 Anu ati alafia lati ọdọ Olọrun baba wa ati Krist Jesu Olugbala wa Titu 1 : 4 ati ti Olugbala wa Titu 2 : 13.

Li o da wa si lori ọpọlọpọ npasẹ Jesu Krist Olugbala wa Titu 3:6 Bi o ti sọ di pipe o wa di orisun igbala ainipẹkun fun gbogbo awọn ti o gbọ tirẹ Heberu 5 : 9.

Iwe awọn ẹnikeji wa sọ bayi wipe awọn ti wọn gba Jesu gbọ, ao gbe wọn ga ju awọn ti ko gbaa gbọ lọ ati awọn ti ko gbaa gbọ laiye kan to mbọ. Ki yio si Oluranlọwọ fun wọn Alukurani Surat 3 ayat 54. de 56.

Ara ninu Oluwa, ko si ariyanjiyan kan nipa igbala Jesu bi o ba ṣe ifẹ rẹ ati Ọlọrun o ti daju wipe Alujanna ni ile mi ati iwọ. Bi ẹnikan ko ba gbagbọ ati de ọdọ Ọlọrun, yio soro fun onitọhun yẹn.

Iwọ ha mura tan lati gba a bi ? Ki o si ṣe igbagbọ lebo ti ko ba ṣee gba taara. O ti daju wipe emi ko ni fi ẹlesin silẹ ki mba ẹlẹṣẹ lọ.

Jesu wi fun ole ọwọ ọtun re wipe loni ni iwọ yio wa pẹlu mi ni paradise

Alafia Ọlọrun ati Ore-Ọfẹ lati Ọdọ Jesu Krist Olugbala wa ki o wa pẹlu Olukuluku nyin.

# A B D Olowe

A. Agbẹjẹ gba wọn la tan nwọn ni ki a pa a ni panṣa

B. Bi O'ode ko ku, ode rẹ ki hu gbẹgi.

D. Dẹngẹ tutu lẹhin u, o gbona ninu

E. Ebi ko pa Imale, o ni on ko ki jẹ aja, Ebi pa Sule o j'ọbọ

Ẹ. Ẹniti o fẹ arẹwa fẹ iyọnu, ẹni gbogb ni iba wọn tan

F. Firi n'idi ọkẹ, a lọ k'olohu digbe

G. Giri lẹhin aṣ dodo akọ maa t'osika lẹhin

GB. Gbolohun kan ba ọrọ jẹ, gbolohun kan tun ọrọ ṣe

H. Hamha ni ọpọlọpọ fi ga ju alamu lọ

I. Ilara alaju ni mu wọn gba jẹ, ni mu wọn ṣẹṣọ

J. Yọyọ Agbo nii mu Agbo niyi Ọla baba ni mu ọmọ yan

K. Ko si ẹniti nṣika ti Ọlọrun ko ni da lẹjọ

L. Lakanlaka ko ṣefi laja ọmọ e-egun ko ṣe fi ṣe ọmọ Iyawo.

M. Malu ti ko ni iru; Oluwa ni iba l'eṣinṣin,

N. Nwọn ni, Amukun, ẹru rẹ wọ" o ni "Lati ilẹ lo ti wọ wa"

O. Ojọ owurọ ti ibi olowa ninu Olowo gelẹ Iwofo gelẹ tẹ'

Ọ. Ọrọ pupọ ki kun agbọn

P. Pipẹ ni yio pẹ, akololo yio pe baba

R. Kiro ni ti enia, ṣise ni ti Ọlọrun,

S. Sisunmọ ni, ni a nmọ iṣẹ ẹni, enia gbe okere niyi,

Ṣ. Ṣokoto ti nṣiṣẹ aran ko bọ oko,

T. Tẹtẹrẹgun ti l'omi tẹ ki ojo to de,

W. Were dun wo ko l'ọmọ

Y. Yinniyinni nii ni k'ẹ ṣe mi,

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 18) Ọrọ kan mbẹ ni fun ọ ti o nfẹ amojuto, ṣọra rẹ ki o mọ iru gẹgebi o ti se ma da si ọrọ na, Nṣe ni ki o mu suru; masi ṣe gbọn pupọ ki o ṣe bi ọmọluwabi, masi ṣe jiyan.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Arẹ le mu ọ ni ọwọ owurọ loni, nṣe ni ki o lọ rẹ ara rẹ tẹ ki o si sun. ọrọ kan yio ṣẹlẹ eyiti yio mu ara rẹ sọji iwọ yio si jẹ igbadun pẹlu awọn ọrẹ rẹ.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ohun kan ti ko ni dun mọ ọ ninu yio ṣẹlẹ si sakani awọn to yi ọ ka loni, nitorina ki o la oju rẹ silẹ ko maṣe ṣe aṣeṣa, Nkan na yio gba iyi lọdọ rẹ ni ọwọ owurọ, ma si ṣe duro fun ẹnikan.

TAURUS (April 21 - May 21) Bi iwọ yio ba ṣe idajọ lori ohun kan, nṣe ni ki o gbe tọtun tosi wo, ki o si mọ bi eyiti o kan ọ nibẹ ti to. Maṣe da si ara rẹ lọrun nitoripe ijọnabọn kekere yio ṣẹlẹ nibẹ ti yio si gba ọ ni asiko pupọ.

GEMINI (May 22 - June 21) Li owurọ ọjọ oni, irohin aladun kan yio ṣẹlẹ si ọ, ohun kan ti o ti gba yio ṣe ọ ni anfani, sinmi loni ki o si lọ dubulẹ.

CANCER )June 22 - July 22) Ṣọra rẹ loni, ki o mọ iru awọn enia ti iwọ yio ba pa ohun ti o ti ṣeleri rẹ fun enia enia maṣe alaimuṣẹ maṣe lo akoka rẹ danu nipa ọrọ ti ko to ọrọ.

LEO. (July 23-Aug. 23) Maṣe gbọn pupọju ki o ba le ri nkan se toju ara rẹ, o fẹran lati ma foju si ọrọ olọro. Ṣọra ki ọrọ ọlọro ma di tirẹ loni

VIRGO (Aug. 24-Sep. 23) Ọrọ kọrọ ti o ba dasi loni yio ma jo gbogbo enia loju ni, inu gbogbo enia ti o ba ba pade loni nṣe ni inu wọn yio ma dun siọ Maṣe jẹki awọn opurọ tan ọ jẹ

LIBRA (Sept 24-Oct. 2.) Sọra loni, ki o lọ mọ gẹgẹbi o ti ṣe nna owo, masi ṣe fọkansi ọrọ ti awọn enia nsọ.

SCORPIO (Oct 23- Nov 22) O dara ki o ma ro ọrọ ki o to sọ, ki adanwo rẹ maba ni ipalara. O tọ ki o si sa fun ijọngbọn.

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec. 21) Amodi kekere kan yio se ọ,' mase jẹki ara tabi aisan gbe ọ de mọle ki o si din wahala rẹ ku

SAGITTARIUS (Dec 22 - Jan 20) Ṣọra nipa ọrọ kan ti ẹnikan yio sọ ti yio si ba gbogbo ọrọ otitọ ti o ti nsọ jẹ awọn ẹlomiran yio ri si ọrọ rẹ ni ọwọ asalẹ ṣ iri rẹ yio si bo, ohun kan ti o ti nfẹ yio ṣẹ.

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹta oṣu karun (3/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akọwe

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
Modupẹ Pri ting Press
16 Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ

ma a Ka Iwe Irohin
Imọlẹ Lojojumọ

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE APRIL 27 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejin rin |
| ABẸOKUTA — — — — | Ijoko, Berẹkodo, Aṣu, Wasinmi, Owode |
| IBADAN — — — — — | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJEBU — — — — — | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJESHA — — — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| EGBADO — — — — — | Alagba, Ilaro, Oja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI — — — — — | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ IṢẸGUN APRIL 28 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Ọbun-Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA — — — — | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN — — — — — | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU — — — — — — | Ilishan, Isara, Imodi. |
| JẸSHA — — — — — — | Ẹpe, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| ẸGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ'RU APRIL 29 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin. |
| ABẸOKUTA — — — — | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN — — — — — | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU — — — — — — | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| IJẸSHA — — — — | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO — — — — — | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI — — — — — — | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ APRIL 30 (THURSDY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja Agege, Ebute-Ero Ojọ Ajido |
| ABẸOKUTA — — — — | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN — — — — | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU — — — — — — | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye. Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| JẸ SHA — — — — — | Ijẹbu-Ijẹsha Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, |
| ẸGBADO — — — — — | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ẸTI MAY 1 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA — — — — | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasnimi Owode |
| IBADAN — — — — — | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU — — — — — | Aiyepe, Sagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA — — — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Il |
| ẸGBADO — — — — — | Alagba, Ilaro, Oja-Ọdan, Suwa, Iboro |
| EKITI — — — — — | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ABAMẸTA MAY 2 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye,Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA — — — — — | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN — — — — — | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU — — — — — — | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe Iṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA — — — — — — | Ẹpẹ, Ilọba. Imuroko, Erinmọọ Iiaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ AIKU MAY 3 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagrey |
| ABẸOKUTA — — — — — | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN — — — — — — | Itoko, ojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU — — — — — — — — | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwa Omu Mamu |
| IJẸSHA — — — — — — — | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO — — — — — — — | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owod |
| EKITI — — — — — — — | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AJE MAY 4 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege |
| ABẸOKUTA — — — — | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN — — — — | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU — — — — — | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope |
| IJẸSHA — — — — — | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijebu-Ijẹsha |
| ẸGBADO — — — — | kasilo-Idiẹmi |
| EKITI — — — — — | Okemesi, Ifaki. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJO'NGBORO

### YABA

O ju gba gbogbo enia ti fon Ole kan ti o fọ iyara Ọgbẹ́i Joseph Ogumah ti o ji Redio kan ti iye owo rẹ jẹ (£8 : 10/) gbe ni nọmba 11, Mọkẹyẹ. Ọdaran na yio farahan niwaju adajọ ni Owurọ yi.

### EKO

Awọn Ọlọpa ti mu ọdakan, ti o gba pọnun mejilelogun abọ (£22 : 10s) fun Alhaja Nimọta Thompson ti o ngbe 4, Idi Ita Street Eko, ṣugbọn ọdaran na ko fi owo na iiṣe fun Alhaja

### YABA

Awọn Ọlọpa ti mu ọkunrin kan, nitoripe o ji garawa kan gbe, bi awọn Ọlọpa ti mu ọdaran na ni, o ba fon Ọlọpa ni £1. No K/6 6401960, ọdaran na yio fi ara han niwaju adajọ ni owuro yi.

### EBUTE-MẸTTA

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati mọto kan, LD 4430 kọlu alalupupu kan Nọ. LH 8460, lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe eniti o farapa lọ si ile Iwosan Igbobi.

### EKO

Obinrin kan, Iyaafin, Adeyinka Alapafuja, ti o ngbe nọmba 20, Apọngbọn Street, ni alupupu kan. Nọ. LC 9562 gbelulẹ nigbati o nkọja ni opopo Adeniji Adele, lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe obinrin na lọ si Ile-Iwosan Eko.

### MUSHIN

Ọkunrin kan David Ajimoko ti o ngbe 42, Palm Avenue ni mọto kan, No WK 1817 gbe ṣubu lori basikulu, lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe ọkunrin na lọ si Ile iwosan fun itọju

### ỌTTỌ

Awọn Ọlọpa ti mu ọkunrin kan Emmanuel Ojẹdile ti o o ngbe 4, Ajọsẹ Lane, Ajegunlẹ nitoripe o wa mọto rẹ, nomba Z 2566 pa Iyaafin Ajoro Oki, Nwọn ti gbe oku iya na lọ si Ile iwosan lakulaku fun ayẹwo.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 590 MONDAY, APRIL 27, 1964 (2D)


## Obinrin Kan Bimọ Mẹta Lẹ'KanṢọṣọ

SAPẸLẸ:- Idunnu subu lu ayọ, ayọ si subu l u oyin fun gbogbo enia ẹbi Erifea nigbati irohin kan wọn pe, Ọkan ninu awọn ẹbi wọn, Iyaafin Felica Erifeta bi ọmọ mẹta l ẹkan ṣoṣo ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ninu Ile itọju awọn aboyun.

Irohin fi ye wa pe, nigbati irohin¡ de si etigbọ ọkọ rẹ pe ọmọ m.ta n iyawo on bi, ko ranti de fila ti o fi sare de Ile itọju awọn aboyun f u n ayọ ti o nyọ.

Ọga alaṣẹ Ile itọju awọn aboyun na, Dokita C. A. Ifeakandu sọ fun oniwe irohin wa ti o wa ninu ilu na pe, meji ninu awọn ọmọ na ni ọkunrin, ọkan yoku si jẹ ọmọbinrin.

Dokita na tun ṣ e afikun ninu ọrọ rẹ pe, alafia ni iya awọn ọmọ na wa ati awọn ọ m ọ rẹ mẹtẹta ko s i nkankan ti o ṣe awọn ọmọ na ati iya wọn.

Dokita na ni on ko le sọ ọjọ ti iya awọn ọmọ na yio kuro ni Ile Itọju awọn aboyun, nitoripe' awọn fẹ koduro si Ile itọju na ki awọn fi ri i wipe, itọju wa fun awọn ọmọ na ati iya wọn.

Ṣugbọn nwọn lero pe ko ni kuro ni Ile itọju awọn alaboyun na ninu ọsẹ yi, o di ọsẹ ti mbọ.

# ẸNITI O JI ỌMỌ GBE WẸWỌN ỌDUN MẸTA

IJẸBU-ODE:— Ọgbẹni Chailes Madarikan, adajọ Agba ile ẹjọ giga Ijẹbu-Ode ṣe idajọ pe ki Ọdaran kan, Iyaafin Falilatu Kadiri, ẹni ogun ọdun ti o wa ninu oyun oṣu mẹfa o lọ si ẹwọn ọdun mẹta onişẹ aṣekara nitoripe o ji ọmọ oṣu mẹfa kan gbe.

Siwaju eyi ni awọn abanirojọ pataki fun Ijọba ti ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe, ni ọjọ kini oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni ọdaran na lọ sinu ile kan ni nọmba 6, Rest House Ijẹbu Ode.

Nigbati o de inu ile na, ko ba Ọgbẹni ati Iyaafin Zacheaus Afọlọrunṣọ nile, o si ba ọmọ ọdọ wọn kan nile ti o mba ọmọ wọn Adesuji Olusẹsan ọmọ oṣu mẹfa ti nwọn mba ṣere.

Bi obinrin na ti ri ọmọ na ti o mba ọmọ ṣere, o bere pe nibo ni awọn obi rẹ wa, ọmọ na si sọ fun un pe, nwọn ko si nile, nwọn ni ọdaran na ba ni on yio duro de wọn, ki o gbe apoti fun on ki on fi joko.

Ko pẹ pupọ ti o joko ni ọmọ tuntun na ba nsunkun Adekunle si sọ fun u pe, boya ọmọ na fẹ mu omi ni, ki o gba ọmọ na fun on ki on sare lọ bu omi ninu amu, ṣugbọn nigbati Adekunle yio fi bu omi de, ọdaran na ti gbe ọmọ lọ.

Nigbati ọmọ na de, ko ba ọdaran na mọ, o ti gbe ọmọ salọ, ni ọmọ na ba nkigbe kakiri gbogbo ilu, nigbati awọn obi ọmọ na de ni nwọn ba sare lọ fi ọrọ na han awọn Ọlọpa ni Teşan.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpanu ba bẹrẹsi wa ọmọ na kiri, awọn Ọlọpa si fi fọto ọmọ na ranṣẹ si awọn oniwe irohin lati tẹ jade.

Ṣugbọn nigbati o di ọjọ kẹrin ni awọn Olọpanu ba ri ọdaran na mu pẹlu ọmọ olọmọ lọwọ rẹ, o si ti fa irun fun ọmọ na ti o fi jẹ wipe bi igba onibara ni ori ọmọ na ndan.

Ninu ẹjọ ti ọdaran na ro lati fi gba ara rẹ kalẹ, o sọ fun Ile ẹjọ pe, irọ ni g b o g b o ẹjọ ti nwọn ro mọ on.

Ọdaran na ni obinrin kan, Ashabi Oṣeni ni o wa gbe ọmọ na fun on ni ọjọ kẹta oṣu na pe ki on maa tọju ọmọ na fun on titi ti on yio fi ti ibiti on nlọ de.

O ni, ni on ba gba ọmọ na silẹ lọwọ rẹ pe, ki o wa gba ọmọ na ti o ba de, ṣugbọn lati igbati o ti gbe ọmọ na fun on, ko tun wa gba ọmọ na mọ.

Nigbati ọdaran na rojọ tan, ni a d a j ọ agba na, Ọgbẹni Madarikan wa sọpe "Ẹṣẹ nla gbaa ni o ti ṣe, o ti mu ọmọde ti ko ti mọ nkankan jẹ oro iya lainidi, o ko si ṣe anu fun ọmọ na.

Emi paapa ko ri idi kan tabi idi keji ti mo le fi ṣe anọ fun ọ. Kini o fẹ sọ ki nto bu nkan rẹ ọ lara?"

Ọdaran na bẹbẹ pe ki adajọ ṣe anu fun on, ni adajọ ba ni ki o lọ fi ẹwọn ọdun mẹta onişẹ aṣekara jura

LATI OJU EWE KINI

on ko awọn nkan ija ogun.

Ọgbẹni Durand ṣe alaye fun ijoko awọn adajọ na pe, o ya gbogbo aiye lẹnu lati ri wipe, awọn Ọlọpa ko le mu Dokita Maja lori gbogbo ọrọ ti nwọn gbọ ti, ẹlẹri meji tabi mẹta si ti sọ niwaju Ile ẹjọ.

Lẹhinna ni ọgbẹni Olu-Ayọọla tun ṣe alaye niwaju Igbimọ Ijoko awọn adajọ na, paapa julọ lori ọrọ ọgbẹni Lateef Jakande.

O ṣe alaye pe, awọn adajọ gbọdọ fi ọgbẹni Jakande silẹ nitoripe, ko lọ si Ghana ko si kọ iṣẹ ogun bẹni ko gbimọpọ pẹlu ẹnikan lati



Latifu Jakande

gbogun ti Ọbabinrin Gẹẹsi ki nwọn si fi ipa gba akoso Apapọ Ijọba Naijiria.

Ọgbẹni Olu-Ayọọla ṣe alaye pe, ohun ti Jakande ṣe lasan ni wipe, o san owo fun ọgbẹni Oleari ati Oboh ko si mọ ohun ti nwọn fẹ fi owo ṣe.

Ọgbẹni Oln. Ayọọla tun ṣe alaye pe, owo ti jakande san fun awọn enia na ki iṣe owo Jakande, owo „Allied„ Newspapers ni ẹgbẹ Afẹnifẹre lo ni owo, awọn lo si ni Allied Newspapers,

Lẹhinti ọgbẹni Olu Ayọọla pari ọrọ rẹ niwaju adajọ, ni ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya bẹrẹ ọrọ tirẹ.

Awọn enia mẹfa ni ọgbẹni Ọdẹsanya yio gbẹnuṣe fun ninu Ile ẹjọ na, Awọn enia mẹfa na ni wọnyi.

Ọgbẹn M. A. Omiṣade, Gabby Shasọrẹ, Adyiga Adesanya, S. J. Umurẹn, U. I. Nwaobiala ati S. A Otubanyọ

Enia mẹrin ni Ọgbẹni Olu Ayọọla gbẹnu ṣe fun ninu Ile ẹjọ na, awọn enia mẹrin na ni wọnyi:-

Ọgbẹni Ayọ Akinsanya S. T. Ọrẹdẹhin, Simeon Oyesile Ọgbẹni L. K. Jakande ati Ọgbẹni J. O Lawanson.

Oniwe irohin wa Ejongboro fi ye wa pe Ọgbẹni Ọdẹsanya ni yio tun maa ba, ọrọ rẹ lọ niwaju awọn adajọ ni owurọ yi.

Oniwe irohin wa ti lọ, bi nwọn ba si ti sọ ọrọ na si, ẹo maa gbọ, ninu iwe wa ọla .

Bi o ba fẹ mọ bi ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọlọ ti ṣe nlọ, iwe kan na ti o le ka, ti o si le fun ọ ni ẹkunrẹrẹ alaye nipa ọrọ na ni iwe IROHIN IMỌLẸ, nitorina maa ka Iwe na ni Ojojumọ.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 26/4/64